# JEGEDE ASỌ'DE TABI O SUN NI, ORUN KE!


AWOGBA
omode fun Giri, Eyi, Hihu-ehin, Otere.
Ra Tire Ni Ile Egbogi
— ISE —
OLODUMARE
Ibadan ati Eko





# ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO



LADIES BRASSIERES
2/-6d, 3/- 4/-6d & 5/-6d each.
Obtainable at :-
A. B. AKINYEMI
10A, Moloney Bridge St
LAGOS.



VOL VII No. 438 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA OCTOBER 22, 1955 IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI. (2)


JEGEDE ASO'DE TABI OSUN NI ORUN KE!



Oro ejo na dori-ko-d'ori, O tun d'ori Emanuel Jegede miran (Eleyi ki ise Samuel Jegede ti Njemanze o,) nigbati won tun bere ejo na ni Kotu nla ni Ikeja ni ojo kokandinlogun osu yi, ni Olopa to gba oro lenu awon odaran enia na soro,

Ni ojo keji, Loya C.O. Ogunbanjo fi han Adajo Ogbeni Adetokunbo Ademola, wipe ko si ejo fun Abudu Aluko odaran kefa ninu gbogbo ejo ti nwon ro, Adajo si gba be, o si da sile ki o ma lo ni alafia.

Eniti o koko wa jeri gbe awon odaran na ni Oloye Oshowemimo Isikalu ti ise Otunbamojo ti Ikorodu, nigbati Oloye S.L. Akintola mbi lere nipa isele yi, o so wipe, on mo Bolaji Kasali, Ogbole paraku enia ni ise, ko-da bi o ba ja lule lati ori Petesi meta po, ko ni farapa,

Odaran keji Rufai Odutala bo sinu Apoti o so wipe ore on pataki ni Bolaji Kasali ni nkan bi odun meje sehin, ni asiko na, Ole tara ni awon mejeji, lehinti nwon ti ju awon se'won ni on siwo ninu ise ole sugbon Bolaji Kasali ko siwo ninu ise ole jija. o si se gbogbo eri ti nwon je mo lara.

# Oba Joel Adeboye I.

## Orimolusi Ijebu - Igbo



ENIA NLA ATI ALAGBARA Joel 2: 2

Eni'l gbogbo enia nfe sugbon ti Olorun fe ju wa lo ni ijoba Oga - Ogo.

TITI AIYE L'AWA YIO MA RANTI RE, OBA ONINURE.

B'ojo ti yo, T'ewo la laro,
Beni Ijebu - Igbo yio tubo
L'agbara si i, L'otito si i,
L'adun si i, L'ewa si i,
B'ibanuje iku Adeboye ti le po to,
Sibesibe Ijebu - Igbo sinmi le
Ife Olorun, Igbagbo ti ki-iye,
Igbokanle Oluwa ti ki itase
Alagborandun, Olufe wa, Oba wa,
Joel Sowunmi Adeboye I.
O DIGBOSE O!!!

Akanse Isin ni Iranti Oba yi wa ni agogo mewa aro ola ni Ile - Isin Ijo C. M. S Ojowo - Atikori, Ijebu-Igbo. Olori Alufa Agba S. Odutola ni yio se iwasu,


# THE NATIONAL BANK

OF NIGERIA LIMITED

Ile ifi Owo pamosi yi
Nfi ona owo han eni
Bi o ba fe je onisowo pataki ao
tan o lowo nipa wipe ao to o
si ona ti o dara, ao la ojn re
si Ona owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni atun nse iranlowo fun
gbogbo oja ile wa ti anta si agbaiye.

ILE ISE WA NI EKO:-
37, MARINA, P. O. BOX 508, LAGOS
WON ASOJU WA NILU OB NIYI
THE NATIONAL PROVINCIAL BANK
(Overseas Branch)
1. PRINCESS STREET LONDON E. C. 2.
THE COMPTOIR NATIONAL DESCOMPTE DE PARIS
8/13, KING WILLIAMS STREET, LONDON E. C. 4.

## Asoju Ilu Naijiria Ninu Oko Ofurufu



Aworan ti e nwo ninu iwe wa yi niti Olola Alhaji Abudu Maliki ti ise asoju (Commissioner akoko fun Oke—Oya (Northern-Nigeria) nilu Oyinbo nigbati o wo oko Ofurufu yi ilu London ka lo gunle si Ibudo Oko Ofurufu ni Heathrow.

Ninu aworan yi, e o ri Ogbeni Abdul Maliki ti o mba awa'ko Ofurufu na soro ki oko to si. Asoju yi so wipe on gbadun oko na, on si ri oye atata ninu re.

Ni Ibudo Oko Ofurufu ti London o se abewo awon ile-ise gbogbo nibe.


## IWE IREPO OTITO

Iwe Irepo Otito yi ni Agbara
Idide enia dudu nipa Ijoba Ominira.
Asa ati Esin ibile tiwa. O
KUN FUN OGBON ATI EKO.
O wa fun tita
3/-6d fun Eyokan, owo ifiranse si Idale 3d
36/- fun Mejila,
Lati Owo O OSONAIKE
14, Bridge Street, Lagos


## PUBLIC NOTICE

### H. M. S. "SPARROW" TO VISIT LAGOS

By courtesy of the Commander-in-Chief, South Atlantic, 300 members of the public will be allowed to go aboard H.M.S. Sparrow from 2.30 p.m, to 4.30 p.m. on Friday 28 October. Tickets will be issued at the Office of the Chief Administrative Officer, Lagos on Wednesday 26th October between 8 and 9 a.m. Not more than two tickets will be given to one person.

The Chief Education Officer, Lagos, will arrange the visit of 300 school children to the ship between 2.30 p.m, and 4.30 p.m. on Monday 31th October.

## Egbe Isowopo Awon Agbe

AGEGE. Ni ojo kerin osu yi ni awon enia pataki merin gegebi Ifo lati ma lo ba awon Agbe soro ni ibiti nwon ba gbe wa, eyi je asotele ise won. Awon enia merin na ni Ogbeni Alex. O. Williams ti ise Alakoso (President) Egbe, S. C. Sheojo Akowe Egbe, J. M. Odesilo ati J. B. Somefun.

Awon eni na de Ifo ni dede agogo mejila osan, Ogbeni M. F. Beckley, oludasile egbe ti Ifo ti ise igbakeji Alakoso (Vice President) egbe ti o ko won l'ona, o si mu won lo si ile-ise egbe (Union Secretariat) nibiti nwon ti se ipade na Lehinti a ti fi awon Iko egbe han gbogbo ijoko na tan ni Ogbeni Williams bo s'ori aga, o si fi adura kukuru si ipade na,

Ninu oro ti Ogbeni Williams so o se alaye yekeyeke wipe egbe yi ko ribi egbe agbe ti nwon ti se ri, a da eyi sile fun isowopo gbogbo omo egbe ni, olukuluku ni yio si ni enu ninu oro egbe, yio si fi oju ri ketekete ohunkohun ti egbe ba nse, o si kesi awon agbe Ifo ti oja Koka wipe ki nwon o jigiri si ise won, ki nwon si sowopo pelu egbe lori ohun to ba je ire awon agbe, bi ti owo yiya ati tita ohun ogbin won.

Ogbeni M. F. Beckley ki awon Iko to wa na, o si gba won ni iyanju lati sowopo larin egbe.

Ogbeni Solabu dupe lowo Alaga fun alaye oro re, pataki lori tita ohun ogbin won ti yio ma a bosi dede pelu owo ti o joju. O si so wipe t'owo-t'ese on ni on fi gba.

Alaga tun soro lori ise ododo fun enikeni ninu omo egbe, ibase Akapo owo egbe tabi Alakoso egbe tabi Akowe egbe, wipe enikeni to ba ni lati se ise nipa owo egbe ni lati je enia pataki ninu ododo sise laiko ni se ibaje to le fa oro a npe olopa lati se iwadi wa,

Ogbeni S, A. Adelari dupe lowo awon Iko to wa ba won soro, o si dupe lowo Ogbeni Beckley fun ise re to nse larin awon Agbe ti Ifo, o si se abere nipa ti owo yiya, eyiti a nilati san kia ati eyiti a le lo pe ki a to san? Alaga si laye gbogbo ijoko na, o si te won l'orun.

Ogbeni E. O, Obadina bere bi Egbe yi ni agbara lati diyele ohun ogbin bi Koko, bi iye ti awon oyinbo Onisowo ba da le ba kere si owo ti agbe fi mu jade? o si daruko Ologbe Oladipo Akeredolu-Ale gegebi o ti se atilehin fun awon Agbe nigba aiye re,

Alakoso Egbe si se alaye fun wipe lati fi kun owo koko ki ise ise owo enikan, O si daruko awon enia pataki-pataki die bi Olola S.L. Akintola A. Obisesan Sanda ati awon enia ti nwon ti sise ribiribi, ti nwon si tun nse lowo-lowo fun atilehin awon Agbe. O si mu da won l'oju wipe Egbe yio ma ba Ijoba Iwo-Orun soro pelu gbogbo agbara won lati lewa ire fun awon Agbe.

Ogbeni Beckley gba won ni iyanju wipe ki a mura giri, ki nwon mase jeki eka egbe ti Ifo lo si okun-igbagbe. Lehin eyi ni gbogbo omo egbe bere si san owo-ifilele ti won. Awa mu ipade wa si ipari ni dede agogo meta.

Lehinna ni nwon wa fun awon Iko egbe ni ipanu nile Ogbeni E.O. Obadina ti ise Alakoso eka Egbe ti Ifo.

Die ninu awon to peju-pese sibi ipade na ni awon Ogbeni M.F. Beckley, D.C. Adenekan, E.O, Obadina, S.A. Solabu S.O Alli, S. Oladele, S. Oyedeji, T.O Mobolade, J B Ayorinde, ati S.A Adebari,

Awon Iko Egbe pada de Agege ni agogo marun irole.

## Oku Olomo Gege L'ao gbe

IJEBU—ODE. Iya oninure ti anpe ni Adefowora Onikosi se alaisi ni ile re 3, Ipamu Street, Ijebu-Ode laipe yi. Iya na to omo odun marundin-logorin ki o to fi aiye sile.

Onisin Musulumi ni iya na nse, o ni inu rere, o si je alanu enia, a se isinku re ni Ite-oku Imale, larin opolopo ebi, omo, ore ati Ojulumo.

Iya rere na fi omo meta

(Wo oju ewe keje)

# Ipade Ipari Odun Kan

Awon IgbimoOselu Eko (Lagos Town Council) se ipade ipari odun kan ti a ti yan awon olola enia na sinu Igbimo Aselu Eko, lati se eto yiyan Alaga Igbimo na, (Chairman) gegebi o ti wa ninu Ofin Igbimo wipe ni ododun ni ao ma yan Alaga.

Alaiyeluwa Qba Adeniji Adele II ti ise Alakoso



ALAIYELUWA QBA ADELE KEJI

(President) Ajo Igbimo na soro iwuri pupo lehin ti nwon ti tun yan Qgbeni A. O Lawson si ipo Alaga ni ekeji. Lehinti afinju oba Adele ti se aponle awon osise ile ise Munisipa Eko ni isori-isori tan, ni o wa so wipe gegebi Alakoso Igbimo yi ati Alaiyeluwa Qba Ilu Eko ti o je ilu pataki julo ni ile Naijiria, o je ayo funon lati fi se fuja wipe ni asiko ti nwon fo (Dissolved) gbogbo Igbimo ni opolopo ilu, ti ilu Eko duro gboingboin,

Alaiyeluwa tun ran awon Igbimo leti nipa ti Ilewe Ofe fun awon omo wa wipe ki nwon mase fi jafara nigbati asiko na ba to,

Lehin eyi ni nwon yan awon Igbimo ti yio se eto yiyan orisirisi Igbimo fun ise eto ilu Eko

Qgbeni Lawson ti nwon tun yan si ipo Alaga si dupe gidigidi fun yiyan ti a tun yan on yi, o si gba awon olola enia olugbimo ni iyanju wipe ki won mase ju ara nu lori ise won gegebi ti atehinwa, ki awon si fi gbogbo ara sise ailabawon fun ire ilu Eko.




EBUTE TAKORADI TITUN NIBITI A NFI IGI GEDU NIKQ

Ilu Takoradi ti di ebute pataki kan ni apa Iwo Orun ile Africa, nitori ibi ti oko ngunle si, ti asese ko pari laipe yi njeki a tunbo ri aye ko igi gedu niko, a sope gidigidi fun idiko titun yi. Simenti Burham ni a fi ko, nitori on lo lagbara julo ni gbogbo agbaiye. O to iwon adorin odun ti a ti nlo Simenti yi nile enia dudu, on ni a fi ko opolopo ile nlanla ni ilu wonyi, eyiyi je iranlowo pupo ninu idagbasoke ile enia dudu.

BURHAM

PORTLAND CEMENT

# ELETI OFE

A-NIU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
25 Kranka Street, Lagos "ELETI-OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. VII NO. 438 LAGOS SATURDAY OCT. 22 1955.


## Gedegbe L'Eko Wa Abo Re O.

Otito ni oro na to so bayi:- "Eko gba ole, o gba ole, Ero to nrele Eko ki o bu omi suru mu. Kurumo ana'ni, Aganyin ana'ni Adamu-Orisa a paluware l'agbos." Daju-daju gbogbo enyin okawe wa ni yio ri irohin kekere kan ti a te sinu Iwe Irohin wa ose yi.

Irohin na ni wipe awon Egbe omo Ile Ibo se ipanupo lati ko ilewe ti won silu Eko ti omo ilu Eko ati omo ilu miran ko ni le de, nitoripe ede ilu won ati iwa ilu won ni yio je okan pataki ninu eko ti ao ma a ko won nibe.

Eyi ara! nje enyin okawe wa gbo irufe eyi ri? lati aiyed'aiye ninu Eko ilewe gbogbo-gbo ni awon Olota ilu wa ma nko sugbon awon Ibo ti ko omi an de nisisiyi, nigbati o ba ya, e o gbo nipa oja Ibo, Ile-Esin Ibo ati Ibudo Ibo ninu Eko.

Abo re o, enyin Yoruba ti e so wipe "GEDEGBE L'EKO WA".

## Awon Egbe Akorin Se Isin Idupe

**Ikorodu** Egbe akorin Ile-esin Iranti Ologbe (Johnson Memorial Methodist Church) se isin idupe ni ile-isin won ni ojo keji osu yi ni agogo mesanabo owuro ojo ose na.

Ile kun, osa bo, fun awon eniyan pataki-pataki l'obinrin l'okunrin ti awon ti iwe pe lati gbogbo ile-Eko wa, ore akanse ti Ogbeni T. Ola Idowu se si awon Akorin titun na ko ti gbogbo re si ndun yanbga.

Iwasu ojo na miringindin nigbati Ogbeni T. Ola Idowu ti ise Alakoso Ile-Isin na so nipa gbogbo inira ati wahala to wa fun Ile-isin na lati ri awon akorin ti awon ti ko daradara, o si dupe lowo Olorun fun wahala won to yori si rere.

Lehinna ni ore idupe wa bere. awon Egbe akorin mu ore wa, ati awon ti a ti iwe pe, gbogbo won ni o mu ore idupe wa. Alufa O. A. George, ti o ti nse alufa Ile-isin na fun nkan bi Ogun odun sehin ni o gbadura, ki a to wa ya aworan po fu iranti ojo na.


# ABOKI



TI IWULO RE LOKIKI
yika Nigeria

OSEMANI lo je fun ilekile
Fun orisirisi AILERA, ntata
Gbogbonse lo je.

RA 100 KAN LONI
nitori AJEBIDAN ni

LODO

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES
Aminigun Street, Phone 189x, Box 295, Ibadan.
FUN ARUN GEHIN-GEHIN


## Oba Obinrin Ilu Gesi Gba Awon Omo Adete Gegebi Omo Fun Itoju

O fere to egberun lona igba enia ti a nreti lati lo wo ifihan ti a sese si ni London lori ise ti won nse lati toju ati lati wo awon adete ti o wa ni gbogbo ile ape asia Gesi san.

Awon ti o pete ifihan yi ni awon egbe ti a npe ni "British Empire Leprosy Relief Association". Gbogbo awon ara Africa, Australia, New Zealand, Canada, America ati India ti won nkoja ni London ni won si ti kowo bo iwe ti won fi ngba alejo ki won le ba ni anfani ati ri ayorisi ise egbe yi ninu itoju awon adete. Opolopo ni o ti nfi owo lele, awon miran si ti tun pinnu lati ma san poun marun lodun fun omo kokan ti arun yi ba mu fun itoju, ati iwosan re. Oba Obinrin ile Gesi ti se Elizabeth Keji ni o ko fi apere iwa rere yi lele gegebi baba re ti se,

Omobinrin kan lati Africa ti oruko re ko han si enikankan ju ti oba obinrin ati awon alagbatoju lo ni Elizabeth keji ntoju nisisiyi. Igba gbogbo ni won si ma nko aworan omo yi ati irohin bi o se ngbadun si lo si afin oba Elizabeth ti a npe ni 'Buckingham Palace'.

Won ti wo awon meji miran ti oba obinrin yi ntoju san.


Chairs For Rent,
Apply :-
OFE
3, Aibu Street,
Lagos.


## Ikomo To Larinrin

**Abidjan** Ni ojo keje osu July, 1955 ni Ogbeni Amusa Ayanbode ati iyawo re Muninatu Abimbola se ikomo jade, Alufa Abudu Layi ni o se isomo l'oruko, awon so omo na ni Ganiyu Ayanwande.

Awon gbajumo po to wa sibi ikomo na, awon egbe Oba-bi-Olorun-kosi ti ise egbe baba omo deju-pese sibe, baba omo si fi jije ati mimu ni orisirisi oti ati Siga te gbogbo won lorun.

Awon enia pataki-pataki ti o wa sibi ikoma jade na ni:-

Ogbeni Raji Oyeleru ti Ise Baba Egbe Bello A. Adedokun, Giwa Gbadamosi, Toyese Amade, Ayanwola Tijani Olaniyi Amusa Oyeleye Lamidi Kekere Olowo Samuel Adeniyi Amusa Olatayo George Ekete, Joseph Raji Faniyi Samuel Adeniji Alufa Kannpa Salawu Oyewo Alufa Daudu Ezekiel Ajagungbade Joseph Iya-Afin Aminatu Farike Hunmani Oyeronke Sifawu Titilola Sittu Oladele Jonatani Babatunde Esikaye Jagun Jimoh Obe, Samuson Idowu Adebisi Driver David Okedigi Salawu Ayandokun. Sule Alaja Opeloyeru Tijani Oyewumi Sittu Arabamibi Tijani Odedele Sanusi Giwa, Josiah Ojurongbe, Oyewole, Adiatu Adebisi. Yunnu Oyewole, Salawu Oladoye, Karimu Oyetunde, Musitafa Oyetunde, Musitafa Oyegbile, Jimoh Alawo, Jimoh Sekoni, Jimoh Ajani, Jimoh Owolade ati Mattew Adedeji. Ki Oluwa fi ire kari gbogbo awon Alabaseye ojo na.

## Awon Ibu Fe Ko Ilewe Fun Awon Omo Won Nilu Eko

Ninu Iwe Irohin ojojumo kan ni a ti rika wipe awon Ibo yio ko Ilewe si ilu Eko, eyiti yio je ti awon omo Ibo nikan lati le ma ko awon omo won ni iwa isedale ati ede Ibo,

A si tun rikaninu Iwe Irohin na wipe Ijoba apapo ti ilu Eko (Federal Government) ti gba fun won lati ko ilewe na.

E kiyesi, enyin Yoruba


Polowo Oja Re
Sinu Iwe Irohin
ELETI-OFE

## Irora Ni Orikerike Hti Isan Ara

BOYA ARUN IGBAROKO LOFA

Ise ti KIDINRIN tabi olo-inu nse ni lati ko gbogbo idoti ti o mbe ni ara danu, Bi awon Kidinrin nwonyi ko ba sise daradara awon idoti ara na yio ma po si, yio si wa di irora fun enia ni orikerike ninu ara.



Ona ti a le gba fi ba gbogbo arun yi ja ni wipe ki a se iranlowo fun Kidinrin lati sise re egbogi ti a npe ni DE WITT'S yi lo le sise na.

Nitorina iru arun bayi ni a sese egbogi na o si je atura o si nfo inu enia mo nipa jije ki Kidinrin bere ise.

A ti dan egbogi DE WITT'S yi wo a si ri wipe o dara, Kakiri gbogbo agbaiye ni a nta Opolopo iwe ni a ti ri gba lati odo awon ti arun yi mba ja, ti awon si ti ri iwosan kiakia.

Kini nda o duro ti iwo ko danwo fun irora tire lo si sobu egbogi lo ra okan wo.

Egbogi DE WITT'S dara fun Ehin didun, Irora Orike Laku regbe Igbaroko ati arun Isan ara.

Ohun ti o dawa loju nipe egbogi DE WITT'S yi je eyiti a se tonitoni gbogbo egbogi o si dara.



**DE WITT'S PILLS**
**for Kidney and Bladder Troubles**

---

**IDAHUN SI IBERE OGBENI AMUDANIYE** Eni-Olorun-da.

KINI A NPE NI IYAWO ILORIN. Gegebi imo ti emi. okunrin kan wa ti o fe lo si Iwo, o wa lo sodo Babalawo wipe ki o ba on wo bi irin ajo on na yio tiri, nigbati Babalawo da Ifa re, o ki bayi wipe " Suru baba iwa " o so fun okunrin na wipe ki o ni suru daradara ni idale ti on nfe lo yi, ki o le ko ere oko bo wa sile.

Okunrin na gbo, o si lo si ilu Iwo na, nigbati o de Iwo, o wo si ile Oba Oniwo, Oba fi si ile kan ti won ko ko di dara ara, nigbati o di ale, ojo bere si ro, o si npa okunrin yi titi ile fi mo. Lowuro ojo keji, okunrin yi lo ki Oba, Oba bi lere wipe, kini ile ti on fi si ti ri? o si da Oba l'ohun wipe Kabiyesi o, ile na dara pupo.

Nigbati ile tun su Oba tun fun ni eni kan, ki o te fi sun, gbogbo ara eni na, okuru werepe ni, werepe ko je ki o ri orun sun titi ile fi mo. Okunrin yi tun lo ki Oba l'owuro, Oba tun bi wipe kini eni ti o fi sun ti ri? o tun wipe Kabiyesi, eni na dara. Opolopo iru okan bawonni ni Oba fi danwo, ti o nso wipe o dara ni

Oba yi bi omobinrin kan ti o ni ewa pupo, o si to fi fun oko, Oba wa pe o bi lere wipe, iwo omo mi, tani iwo yio fe? omo Oba na si dahun wipe alejo to wo si ile Oba ni on yio fe, Oba si fi fun okunrin alejo na.

Nigbati okunrin si pada de ilu re, o wa nse iki'o fun awon enia re wipe Iya-Iwo ni iyen o. nitorina ki enikeni mase ba ja o. Ohun to fa Iyawo wa ni yen o, Aho re o.

Emi ni,
YAKUBU MOJA OPERE.

---

**ILOSIWAJU NLALA TI O WA NINU OWO TI SYRIA ATI ILE GESI NBA ARA WON SE**

A ri ilosiwaju ati itankale ti o fi ese mule daradara ninu owo ti Syria ati ile Gesi nba ara won se. Apere yi fi ara han ninu iyato ati ele'wo ti o wa lori oja won ti odun to koja ati odun yi. O le ni ogorun oke poun ti oja ti odun yi fi gori ti odun ti o koja. Gegebi isiro ti awon igbimo onisowo ti ilu London se, iyato to wa lori owo oja ti Syria ta fun ile Gesi ni odun yi ati eyi ti o koja to egberun lona ogorun poun ati abo. Ohun ogbin ile Syria ti o si nfa owo wa fun ju lati ile Gesi ni owu,

---

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, iko ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode

**OMORELA BABY MIXTURE**
*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*
O wa lodo :—
COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS

---




New recordings of your favourite singers and instrumentalists are always being made on "His Master's Voice" Yellow Label records. Here are some of the latest titles — secure them for your collection . . .

JZ.5631—OWO ORI/ORE MEJI ATATA) Tijani Alabi's (Sakara)
JZ.5632—SIKIRU AKINTUNDE/ALAFIN) Band

JZ.5668—IYERE/IBARIGHA ) Theophilus Walokun's
JZ.5669—ITOJU EBI/KENEMA ) (Ilese) Band

JZ.5686—OMOGE/ONINU MEJI ) Bashiru Alamutu's (Apala)
JZ.5687—ORISIRISI EWU/IRAGBEJE) Band

JZ.5707—OWO LESO AIYE/OLOWO AIYE )
JZ.5708—ITAN AKIYEYE/TOKUNRIN TOBINRIN) S. K. B. Ajao
JZ.5709—KALOWO KARASO/EJONIGBORO) Oru's (Apala) Band

JZ.5710—PATANI/AM ALAGHA YEI) Ijaw Youths' Orchestra
JZ.5711—FRED AGUGU/NINETRY)

JZ.5712—TENIMASUNWON/ILU ALADUN) Seidu Sokoto
JZ.5713—IYAWO AREWA/JAGAJIGI ) (Perento) Band

JZ.5727—ABAN JE/IDERA )
JZ.5755—IGBEKELE/OWOLEGBON) Rosey Show Mambo Orchestra

Recorded in West Africa ☆

**"HIS MASTER'S VOICE"**

The Hallmark of Quality

Now obtainable from all the best stores

Distributors: THE UNITED AFRICA COMPANY LTD

## OKU QLQMQ GEGE L'AO GBE

(O bere l'oju ewe keji)

s'aiye, Iyafin Ramotu A. Shaki, Qgbeni Yaya Onikosi ati E. A. Onikosi pelu opolopo omo-omo.

Ni ojo isinku Iya na, Qgbeni R. A. Shabi ti o nsise ni Elder Dempster l'Eko fi jije ati mimu te opolopo enia l'orun ni nu ile re ni Ijebu-Ode.

Awon to wa sibi isinku na ni Iyafin Aduke Ojobaro Qgbeni Ishola Shabi. Fasasi Shabi, S. Qla. Adams, S. A. Qdunsi, Agbetoba, Qmidan Taira Edidi, O. A. Mabuogunje, Iyafin Modupe Shabi ati Qgbeni Oyewole Sapara.

## Igbeyawo Aladun

EBUTE-METTA Igbeyawo Omidan Ashabi Isaac, Omobinrin bibi Inu Ogbeni S.A Isaac ti ile ise awon Oloko ije (Nig: Railway S/cs Section) pelu Qgbeni Emanuel Ayodele Adebo ti a se laipe yi ni Methodist Churh Ago-Ijaye, Ebutemetta dan o si l'arinrin.

Iyawo wo aso funfun to ndan yinrinyinrin pelu idi Itana olorun atata lowo, baba re ni o si mu wa si Sosi, on na l'o si yonda Iyawo fun oko niwaju Pepe, Qgbeni E.A Oshibajo ni o se igbakeji Qko-iyawo, iyawo re Iyafin Elizabeth Oshibajo sini igbakeji iyawo, Alufa E A Adegbesan ti ise Alufa Sosi na ni o se idapo t'oko-t'aya

Lehin idapo t'oko-t'aya, awon ebi ati Qre ni nwon fi owo siwe idapo na, lehina ni a wa dari lo si Gbogan Lisabi (Lisabi Hall) nibiti ayeye na gbe wa rinle dodo, ti Qgbeni S A Odugbesan Qga Onisiro-Owo nile ise Reluwe se Alakoso aseye na, Ogbeni J Ade Tuyo ni o soro isiri nipa t'oko-t'aya ti oko Iyawo si fesi daradara.

## Iyawo Dun L'osingin Qko Tun Mi Gbe



QLOLA M. T. MBU

Aworan Inu iwe wa yi niti Qlola M. T. Mbu, on ni yio gbeyawo arede loni. awon egbe Island Club yio si gba l'alejo ni ojo ose ola ti ise ojo ketalelogun osu yi.

Ni ojo kedogbon osu yi ni yio si lo bere ise re nilu Oyinbo gegebi asoju ilu Naijiria fun Ijoba Apapo ti ilu Naijiria (Federal Government of Nigeria)

Nje Qlola Mbu d'oniyawo a jo jo jo, a yo.

NOW

AVAILABLE

BUGLES. BADSTAADS
PAINTS DISTEMPERS,

SAFES Etc.
Just Write, Call, Or
Phone 21372

IKORODU TRADING
COMPANY

20/28 Balogun Street.
(P. O. Box 395) Lagos
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN

## Qko Ofurufu Ndabira



Aworan oko iwe wa yi niti Qlola Ahmadu, Sardauna ti ilu Sokoto ti ise Alakoso Ijoba Oke-Qya (Northern Premier) pelu Oba Ilu Gwandu ati oyinbo Qgbeni J. J. Parks ti ise Alakoso awon Egbe Akan'ko Ofurufu nilu oyinbo nibiti nwon ti nwo'ran awon oko Ofurufu ti won fi ndabira l'oke rere loju orun.

Iran yi je pataki ti o si ni igbadun pupo nitoripe eyi ni nwon nse l'odun lati fihan wipe Oko Ofurufu ti Gesi nse je eyiti o pe, ti o si dara ju. Awon Gesi ni o si nse opolopo Oko Ofurufu, awon ero ti a fihan lodun tokoja bi asese se, ni o ti di asepari l'odunni.

Mo Gbadun Siga
Pirate




PIRATE
Je Siga To Dara

## Egbe Ilosiwaju Ti Ilu Ilafin

Awon egbe Ilosiwaju ti ilu Ilafin se ipade alarinrin kan l'Eko ni ojo kerindinlogun osu yi, won si se ipinnu wipe ki Alaiyeluwa Oba Ilafin, awon Agba-gba ati awon Igbimo ba wa se abojuto awon abinrin ilu wa ti nwon nsa kiri wa si ilu Eko, nitoripe won ko fun won ba awon omo-kunrin ati oko won nilu wa.

Nitorina, a nfe ki Ijoba Ibile ati awon Kansilo wa gba oro na ro daradara, awon obinrin ilu wa ti fe lati ba oruko ilu je ni idale, obinrin ti o ba tun sa wa si idale ti nwon ko ba ri, ti o ba tun pada silu wa, ki Alaye ran olopa lo mu, ki won gba ponun marun (£5) lowo re, bi ko ba pada silu wa mo, o dara be imoran ni a da o, ki ise ase o.

A se ipinnu yi nipa aisan ti awon obinrin oko wo'lu wa

O. Alfred S. Ajayi
Alaga Egbe Akowe Egbe

Awon Egbe Ilosiwaju omo ilu

Ilafin nse abere leta'e yi lowo awon omo ibile ilu Ilafin-

(1) Nibo ni e wa eeyin Ilafin?

(2) Nibo ni Ilewe yin wa?

O to asiko fun wa lati ji giri si ohun ti yio je ire ilu wa. a nso'le a nra keke, a ngbe iyawo, sugbon a ko ranti ogun aje-jetan fun awon omo wa ati iran ti o mbo lehin-ola.

Awon iya wa, ati awon baba wa ti Esin ti gba okan won ti nwon nna owo (£6) l'ososu eyiti o je (£72) l'odun kan fun Esin, bi a ba ro ti Ilewe pelu iba dara.

Awa ni omo Ilafin.

## Fani Kayode Fi'po Alaga Sile Fun Oni



A gbo behin wipe Ogbeni R. A. Fani - Kayode f, aye Alaga Igbimo Ibile Ile - Ife sile fun Alaiyeluwa Oba Adesoji Aderemi I. Oba Oni Ile - Ife.

Oro akatakiti kan sele larin Igbimo Ibile lori Ogbeni John Adekemi ti Oni fi j'oye Aguro, pupo ninu awon Olugbimo ko fe ki eniti Oni fi je oye yi wa ba awon joko gegebi Oloye ninu Igbimo Ibile

A si gbo wipe eniti Oba Oni fi je Oye yi je eniti awon Ijo keji ti Alufa S. A. Adeyefa ti ise okan ninu awon Olola ti Ile Igbimo Iwo - Orun ni Ibadan fe yato si Ogbeni Emanuel T. Oladipo ti o ti se ise Wole - wole j, ti awon Ijo Talaka Parapo fe..





### ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajela omode, agb'omola bi or'sa Akokoluko ogun ti eda'mo l'ekun igbona, atata ogun ti np'otutu re warawara A je bi idan, a gba bi etu ibon, O s'abiku d'ikugbagbe, o s'omo ti nhehin l'ore. Iko ri i d'ekun iyonu. Olugbala f'omo ti nyagbe orin O'kapa inu-iwo, o lu Jedi l'alupa: gbogbo abiyamo nye sese, Ela ri i o r'oju, orere rii, o na'gbe bo'ra, Eyi npa'lemo lodoleso. Ore ikoko, kosemani awon abiyamo, eni araiye njijadu ra. O de'lu Ibo, o d'oga, o de'le Hausa, o d'oba. Gbogbo onisegun l'o so pe ko l'egbe, gbogbo omode l'o nfe e fun'lera.

**The Egba Trading Aradan Stores**
18 DENTON BRIDGE ST.,
P. O. BOX 2,
EBUTTE-METTA.


## ASSOCIATION OF RESIDENTS IN CENTRAL LAGOS
BY HADJI A. F MASHA

**The following is for the information of the Public:-** The above **Association is out on the Motto:- "The will of the people is the supreme law"** The Association embrace **all** Residents in Central Lagos **which has been earmarked** for the so-called Lagos Slum Clearance Scheme.

The Association is out to fight with all the constitutional methods and to oppose the so-called Lagos Clearance Scheme. as the Association do not believe that the Scheme is intended for the benefit of the original land-owners, on the following reasons.

(a) That land which will be acquired assessed Value i. e. £100 per plot may be resold at £1000 per plot which will be beyond the capacity of the average original owner.

(b) The the Building to be erected on the reclaimed land will be a mansion of a three or four Storey building not exceeding 8 Rooms in the whole building (according to Density Control).

(c) That the building to be erected will cost more than £8000 which is above the average Capacity of the Original owner if even a mortagage Scheme is involved.


## ABOKI



TI IWULO RE LOKIKI
yika Nigeria

KOSEMANI lo je fun ilekile Fun orisirisi AILERA, atata Gbogbonse lo je.

RA IGO KAN LONI
nitori AJEBIDAN ni

LODO

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES
Amunigun Street, Phone 189x, Box 295, Ibadan.


Printed & Published by The Ebute Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370